AWỌN OHUN PATAKI
NINU IWE ỌSẸ YI
Faṣemojo joye Lọtun
Oju iwe 1
Aworan Awolọwọ
Oju iwe 1
E ranti Oke-Oye
Oju iwe 2
Ma tara Ibokun ṣọnu
Oju iwe 2

# IRAWỌ ★ OBOKUN

Ọrọ nipa atunṣe Ileṣa
Oju iwe 3
Aṣa alade Gẹsi
O iwe 4
Kọṣẹkọṣẹ ati owori
Oju iwe 5
Karubu Serafu ṣe ipade
Oju iwe 6
Odun de, — conupi wa da
Oju iwe 7
Olotu-Igbokegbodo
Oju iwe 8

Vol 4 No. 173 ILESHA MONDAY FEBRUARY 13 1956. IYE OWO: TỌRỌ

# OBABIRIN ATI ỌKỌ RẸ TI BẸRẸ IBẸWO TI ẸKUN IWỌ ORUN



ỌLỌLA S. A. AKINỌLA
On je ọkan ninu awọn asoju ilẹ Ijẹṣa ni igbimọ ijọba Ẹkun Iwọ Orun. Igbimọ na yio ṣe ipade lati ṣe eyẹ ikinikabọ fun Ọbabirin ati ọkọ rẹ lọsẹ yi.

## IKEDE PATAKI

Eyi ni lati kede si etigbọ olukuluku awọn to lowo ninu iṣẹ itẹwe Ijẹṣa (Ijesha Press Ltd.) ti ko ba i ti ri iwe eri (Share Certificate) gba gẹgẹbi ẹnikan ninu awọn to lowo ninu iṣẹ na lati wa si ibi iṣẹ itẹwe Ijẹṣa ni B 14 Okeṣa lati wa gba tirẹ.

Ki ẹniti o wa ni ilu okere kọ iwe ranṣẹ pẹlu (Address) ibiti iwe ti le tẹ lọwọ. Ẹnikẹni ti ko i ti foruko rẹ sọwọ ẹkun tab lakọpe bi "JOSEPH ADEWUMI ADELEKE"

Ki o kọ ranṣẹ. Ki o maṣe kọ ni "J. A. Adeleke" akọkun rabi akọpe ni ofin nfẹ.

ALABOJUTO



ỌLỌLA J. O. FADAHUNSI
On na je ọkan ninu awọn asoju ilẹ Ijẹṣa ni igbimọ ijọba ti Ẹkun Iwọ Orun Nigeria. Oriṣiriṣi eto ayẹyẹ ni ijọba na tiṣe silẹ fun Ọbabirin ati ọkọ rẹ.

# E ra Irawo Obokun Ka

## ỌBABIRIN ATI ỌKỌ RẸ TIDE

Ni ọjọ kesan oṣu yi nigbati ọbabirin ilẹ Gẹsi ati ọkọ rẹ nkọja lọ si Eko, wọn sọ kale fun igba diẹ ni ebute ọkọ ofurufu ni Ibini. Diẹ ninu awọn to pade Ọba nibẹ ni Ọlọla John Rankin Komina ti Ẹkun Iwọ Orun, Ọbafemi Awolọwọ, Olori awọn Oluṣeto Ijọba Ẹkun Iwọ Orun Nigeria. Ọba Alaiyeluwa Akenzua keji, Ọba Alaiyeluwa ti Ibini ati ọpọlọpọ awọn oloye Ibini. Ọlọla S. O. Ighodaro Oluṣeto ilera ati Ọlọla Oloye Anthony Enahoro, ọkan ninu awọn oluṣeto Ijaba.

Lẹhin igbati wọn ti ṣe abẹwo Ibini fun bi wakati kan ni wọn kọja lọ si Eko.

Ni ọjọ kẹwa oṣu yi ni Ọba lọ si ebute ọkọ oju omi ni Apapa. Ogunlọgọ enia lo to sọtun ati si osi oju ọna lati wo Ọba na ati ọkọ rẹ ni ikọja;

Ọkọ oju irin ni kabiyesi na ati ọkọ rẹ bade Ibadan lati Eko; Wọn duro fun igba diẹ ni Abẹokuta. Alaiyeluwa Alake Abẹokuta pẹlu awọn enia pataki pataki lo lọ pade wọn nibi ọkọ.

Lẹhin igbati Ọba na ati ọkọ rẹ ti duro diẹ ni Abẹokuta ni wọn lọ si Ibadan.

Ọjọ Satide ọjẹ kokanla oṣu yi ni Ọba na de Ibadan lati pari ibẹwo ti Ẹkun Iwọ Orun.

Ogunlọgọ awọn ọmọ ile iwe igun mererin Ẹkun Iwọ Orun Nigeria lo ti awọ si Ibadan lati ọjọ kesan oṣu yi lati ṣe ẹyẹ fun Ọbabirin na ati ọkọ rẹ.

Ogunlọgọ ero lo nfojumọ wọ lọ si Ibadan lati ọjọ ti ọba na tide

Ọkọ ile ni Ọba na ati ọkọ rẹ yio wọ lati Ibadan lọ si Eko. Ọna Ijẹbu niwọn yio rin wọn yio si duro diẹ ni ọna Ijẹbu fun ayẹyẹ diẹ.

A gbọ pe awọn ara Ijẹbu pẹlu awọn Ọba ati Ijoye wọn ti mura silẹ lati pade Ọba na ati ọkọ rẹ

## FAṢEMOJO DI LỌTUN

Lati nkan bi oṣu kan sẹhin ti ikede ti jade pe Ọgbẹni Samueil Faṣemojo yio jẹ oye Lọtun Igbaye ni wọn ti nmura silẹ.

Gbogbo awọn ọrẹ, ebi ati awọn aladugbo rẹ lo ti nmura silẹ fun eto inawo oye na.

Nigbati o ti ku bi ọjọ mẹta ni awọn ọrẹ, ana ati awọn ọmọ rẹ to wa ni idalẹ ti nde si Ileṣa.

Ni ọjọ keje oṣu yi ni wọn lọ jẹ oye na ni Afin Kabiyesi Ọwa Alaiyeluwa Ajimọkọ keji

Lẹhin igbati wọn ti ṣe oriṣiriṣi eto nipa oye jijẹ tan ni wọn bu eruku oye si lori ti wọn si fewe oye ba leti.

Lẹhin eyi ni on ati awọn ogunlọgọ ero to wa nibẹ lọ sidi "OBOKUN" gẹgẹbi aṣa idalẹ. Lẹhin ti wọn kuro nibẹ ni wọn jo lọ si ile ọpọlọpọ oloye ki wọn to dari sile lọwọ irọlẹ ọjọ na.

## AKIYESI PATAKI.

A ni ki a filọ fun gbogbo awọn adugbo ti o ba wa ni ilu Ilesha ti ko ba ti ni opo ina rara, tabi eyi ti o ba ni opo ina ṣugbọn ti ko ni waya pe ki iru adugbo bẹ kọ iwe ṣọwọ si ibi iṣẹ Akọwe Igbimọ Ijọba Ileṣa, ki wọn ṣe alaye eyiti ko ba si ni Adugbo wọn ninu eyiti a kọ si oke iwe yi. (Secretary, Ilesha Urban District Council.)

Igbimọ yio ṣe eto ti o bayẹ lati ri pe gbogbo nkan dọgba.

(Sgd.) J. M. AJAYI OBE
Alaga Eto Ina

(Sgd.) G. A. O. ABIỌLA
Akọwe Igbimọ.



ALAIYELUWA ỌBABIRIN ILẸ GẸSI TI BẸRẸ IBẸWO ẸKUN YI

IRAWỌ ★ OBOKUN

ILE IṢẸ B149; ADUGBO OKEṢA, ILEṢA.
P. O. BOX 23, ILEṢA
Telegram: Irawọ Obokun
Vol. 4 No. 173 Monday FEBRUARY 13

IYE OWO "IRAWỌ OBOKUN"

:o:

| | Oṣoṣu | Oṣoṣu-Mẹta | Ọdun |
|---|---|---|---|
| ILEṢA. | Şile kan. | Şile mẹta. | Şile mejila |
| ẸHIN ODI | Şile kan kọbọ meji. | Şi e mẹta ati sisi. | Şile mẹrinla |

## Ẹ MAṢE KỌ OKE-OYE TI

Awọn agbalagba lo ma npa lowe pe bi egungun ẹni ba jo dada iọja nṣe ni ori ma nyọ ni. Ninu awọn ijọ ịa-bi ẹgbẹ onigbagbọ ti enia dudu ti i da silẹ ni ilẹ Nigeria, Ijọ Aposteli jẹ ọkan, ilu Ileṣa ni ikorita rẹ, adugbo Oke Oye ni ibudo wọn.

Ẹ lọ si Oke Oye, ni akọkan ni ile ijọsin nla ti Ijọ Aposteli wa. Ni iwaju rẹ ni ile iwe nla wọn wa, niwaju lọ-hun ni ile ikẹkọ giga wa fun awọn oluko, bi ile ẹkọ awọn oluko n a t i nṣesiwaju i ọ d ọ d u n ni wọn n k ọ akọkun ile: Ni apakan i b ẹ ni ile pupọ wa fun awọn oṣiṣẹ ati o l u k ọ awọn ile iwe wọn. Lẹhin ogunlọgọ awọn ile pataki pataki to wa fun ijọ Aposteli ni Oke-Oye ni ile ẹkọ giga kan wa nibẹ fun awọn obirin.

Nitori awọn ile iwe ati ile ẹkọ giga t'ọkunrin ati t'awọn obirin to wa ni Oke-Oye yi, ati nitori ogunlọgọ awọn to njọsin ni ile ijọsin wọn laika awọn ero to nna awọn ilu Ilerin, Eti-Ọni, Ijẹmba, Irogbo, Ipole, Odo, Iperindo ati bẹ lọ titi, ainiye ero lo ma nrin ọna Isare si Oke-Oye lo-jumọ. Ti a ba wo, ao ripe ṣaṣa adugbo lo wa ni Ileṣa ti ọpọ ero ma nrin bi ti Isare si Oke Oye, papa awọn akẹ-kọ, nitori eyi, a ro wipe o yẹ ki ijọba toribẹ ka isare si Oke-Oye yẹ ni adugbo ti wọn ni lati fi ọda si kiakia.

Ati ka Isare si Oke-Oye yẹ fun ọda ko yawa iẹnu nigbati a gbọ pe lati igbati omi ẹrọ ti de Ileṣa wọn ko i ti ia de Oke-Oye. Lẹhinna, o ku diẹ ki okun ina ala-tanmọlẹ de gada Ora ni wọn da duro. Eyi yani lẹnu pu-pọ nigbati a ronu si iranlọwọ ti omi ẹrọ ati ina iba jẹ fun awọn akẹkọ Oke-oye. Nitorina a bẹ awọn alaṣẹ lati bo-ju anu wo Oke-Oye. Ero ọkan wa nipe wọn ko ni fi iṣẹ su awọn alaṣẹ ile iwe to wa ni Oke-Oye nitori ti a ko ba tori iṣu jẹ epo, o yẹ ki a tori iyọ jẹ.

## KỌṢẸKỌṢẸ ATI OWORI (2)

Ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu to kọja ni a kọ ọrọ nipa itujẹ to wa ninu owori gbigba lọwọ awọn ọkọṣẹ. A ko iti ri idi ti a fi ni lati lodi si ohun ti a sọ nigbana pe niwọn ti ijọba ko ba ti gbowori lọwọ awọn ọmọ ile iwe giga koyẹ ki wọn gba lọwọ awọn to nkọṣẹ.

Ti o ba jẹpe dandan ni wọn fẹ owo lori eṣu tabi lori ẹgba, ohun ti a ṣe akiyesi lati ile ọdun yi fẹrẹ le mu wa daba wipe o yẹ ki awọn ọmọ ile ẹkọ giga mu san owori.

Ẹ lọ si oju agbo ijo, ẹ lọ woran kokoma, ẹ lọ sibi ere Mambo, ẹ lọ woran ni ile igbayo Banuso, ẹo ripe awọn ọmọ ile ẹkọ giga ni nawonawo nibẹ. Ṣaṣa ninu wọn lo le nikan lọ sibi iworan laigbe Ledi (Lady) sẹgbẹ, ṣaṣa ninu wọn lo le dajo laisi igbeleṣẹ awọn ọmọ iyọra. Yatọ si awọn alajẹtan oṣiṣẹ, boya ni a le ri oṣiṣẹ to ngba bi pound mẹwa (£10) loṣu to le nawo fun awọn alamuyale obirin bi awọn ọmọ ile iwe giga mi-ran; sibẹsibẹ wọn ki i san kọbọ owori.

O dunni pe alatẹ ni okete ma nhalẹ mọ, bi ko ba sibẹ, a ko ri idi to fi tọ lati ma gbowori lọwọ awọn ọmọ to nkọṣẹ: Ọpọlọpọ wọn ni ko mọ ọjọ isimi yatọ. Eyi to ba ni alafẹhinti lo nle parọ aṣọ iṣẹ ni irọlẹ; ṣaṣa ninu wọn lo nle ma ranti aṣọ ọ d u n; sibẹ-sibẹ, awọn ni alabulẹ owori yio kọkọ ri lati bu owori fun.

Iba ma jẹ ẹdun ọkan wa bi o ba jẹpe wọn ma nrowori na san pẹlu irọrun Omiran ma nfi odindi oṣu kan silẹ lati lọ soko agbaro nitori atisan owori.

A fi iyọnu Ọlọrun bẹ ijọba lati ṣeto lọna ti awọn to nkọṣẹ ko fi ni pẹlu awọn tiwọn yio bu owori fun.

## Ẹ RAN IRAWỌ OBOKUN LỌWỌ

Lotọ ẹnito ba ṣe ohun tẹnikan ko ṣe ri, oju rẹ yio ri ohun toju ẹnikan ko ri ri. Lotọ ohun ti ẹnikan ko ṣe ri ni pe ki awọn ọmọ orilẹ-ede kan pa ọwọ pọ lati da iṣẹ iwe irohin silẹ. Şugbọn ẹnikan lo ma nṣe nkan ṣiwaju ki ẹlo-miran to ṣe bi ti wọn, nitorina ni a fi gba pe ki i ṣe ẹṣẹ fun Ijẹṣa lati pọwọ pọ da iwe irohin silẹ. A si rope nṣe loyẹki awọn olufẹ, papa awọn Ijẹṣa nibikibi ma ran iṣẹ iwe irohin na lọwọ.

wuri lo ma njẹ fun wa nigbati a ba ri bi awọn Ijẹṣa nibikibi ṣe nfi ifayọ tayọ ra iwe Irawọ Obokun. Şaṣa ojumọ lo ma nwa ti a ki i ri iwe gba pe "a fẹ Irawọ Obokun" nibi, "a fẹ Irawọ Obokun" lọhun. Bi awọn jẹṣa ti ṣe ni inu didun si iwe irohin yi ni awọn ọmọ orilẹ-ede miran ni, nito-ripe ọpọlọpọ iwe idupẹ lati ọdọ awọn enia bẹ lowa lọwọ wa.

"Şugbọn", a ni "ṣugbọn kini kan ba Ajao jẹ, kini na nipe apa rẹ gun iu itan lọ". O dunni lati ṣe akiyesi pe lotitọ ni "jijẹ ẹlẹdẹ jẹ yungba-yungba, ṣugbọn ti sisan owo ẹlẹdẹ di tihan-tihan". Gbogbo enia lo mọ iru ipo ti iṣẹ itẹwe yi wa. Gbogbo enia lo mọ pe iṣẹ na fẹ iranlọwọ. Şugbọn iranlọwọ ti a tọrọ lasiko yi nipe ki ẹniti o ba bawa ra ọja ma sanwo Gbogbo enia lo mọ pe ọbẹ to dun owo lo le ṣe. Nitori eyi ni a fi rope o yẹ ki awọn olubara wa mọ pe nipa sisan owo iwe ti wọn ba ra lọwọ wa lasiko ni a fi le tẹ omiran. Nipa sisan owo iwe ti olukuluku ba nra lasiko ni a fi le rowo oṣiṣẹ san.

Nigbati a si iwe wa wo, ti a wo orukọ awọn to jẹ wa lowo iwe, ti a si ripe awọn ti a wi yi jẹ awọn to mọ nipa iṣowo, ti wọn le mọ pe owo ni a fi nra iwe, owo ni a fi nsanwo gbogbo ohun ti a fi ntẹ iwe na jade lọsọsẹ, ti wọn si ngba iwe na laisanwo, o dun wa pupọ. Nitorina ẹbẹ wa nipe ki awọn to nra iwe wa ma sanwo lasiko ti wọn ba nfẹ ki iṣẹ na ma lọ dede; nitoripe ko dara ki a fi egbo ṣe egbo ile ki a si ma fi da onjẹ kọja. Ẹjọwọ o.



KANSẸLỌ GABRAEL ẸSỌ

On ni Lori ọmọ Ifọṣan on na ni aṣoju wọn ni igbimọ ijọba Ileṣa. Ẹnikan kọwe lọṣẹ yi pe o yẹ ki wọn da ọda si Ifọṣan tabi ki wọn fi simẹnti ṣe eti gọta rẹ.

E FI IROHIN IPADE IGBIMO YIN
SỌWỌ FUN TITẸ JADE NINU
... IRAWO OBOKUN ..

## ẸGBẸ KERUBU SERAFU ṢE IPADE

Kerubu ati Serafu, Ilesa ati agbegbe ṣe ipade kan pataki ti awọn ẹgbẹ ọdọ ti nṣe akọrin fun ijọ yi, o bẹrẹ nile adura wọn ni Oke-Ẹsọ ni ọjọ kọkandinlogbọn oṣu to kọja.

A si ri wipe ti ile ati agbegbe ni o wa si ipade yi (lọkunrin ati lobirin) fun itẹsiwaju ọrọ Oluwa.

Wọn bẹrẹ ipade na ni a g o g o mọkanla arọ, o si pari ni agogo mẹta abọ ọsan. Ogbẹni Abel Fapohunda lo fi adura si ipade na.

Ọrọ bẹrẹ lati ẹnu Ogbẹni Ajọje Ninu ọrọ iṣiwaju, wọn ni idi ti a fi gbe ipade yi kalẹ gẹgẹbi apapọ ọdọ lọkunrin lobirin ti nṣe akọrin fun ijọ yi nile ati agbegbe nipe wọn nfẹ apapọ, wọn ko fẹ ki eto ti wọn yato si ara wọn.

Nipa ifẹ ti o ye koro, ti iru ipade yi bawa, ao ma ni anfani lati ma fi ọrọ Ọlọrun bọ ara wa. Lẹhin igbati wọn ṣe eto ọrọ gbogbo ti o wa ninu ajẹnda wọn tan ni wọn gbọ ọrọ iyanju lati ẹnu Alagba kan lati inu iwe Peteru Kini ẹsẹ ketala de ẹkẹrinla.

Lẹhin eyi pẹlu adura ati orc-ọfẹ, wọn wa lọ jẹun, lẹhin eyi wọn yan Komiti ti yio ṣeto fun ipade ti o mbọ ni 26-2-56.

Wọn ṣe ileri pe gbogbo ohun ti wọn ba nṣe ni yio ma jade ninu iwe yi ni igba miran. Wọn bẹ gbogbo wọn pe ki wọn ma fi ṣọkan lati wa si ipade igbagbogbo, papa ipade ti ọjọ kẹrindinlogbọn oṣu yi.



AFIN ỌBA (BULKINGHAM PALACE)

Ilẹ yi ni Afin nla ti Ọbabirin ati ọkọ rẹ ti jade lati wa bẹ Nigeria wo. Ẹgbẹta iyara (600 rooms) lo wa ninu ile na ṣugbọn ti si gun ju maili kan lọ.



ỌLỌLA S. O. AWOKỌYA

On jẹ ọkan ninu awọn oluṣeto ijọba ti Ẹkun Iwọ Orun Nigeria. On ni oluṣeto nipa ikẹkọ. Ọba obirin ati ọkọ rẹ tide ijọba wọn lalejo lati ọjọ kokanla oṣu yi.



ỌLỌLA ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

On ni (Premier) olori awọn oluṣeto ijọba ti Ẹkun Iwọ Orun, wọn tigba Ọbabirin ilẹ Gẹsi ati ọkọ rẹ Alaiyeluwa lọja ti Edinbuba lalejo lati ọjọ bi mẹta sẹhin

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu

## "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26 52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. " | " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KEJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, ATI 7 JE OWO KANNA

PẸLU TI OJU EWE KEJI.

